ÒDIWỌ̀N ÌTAYỌ BÍ FỌ́NRÁN ÌṢỌWỌ́LÒ-ÈDÈ NÍNÚ ÌWÉ *ORIN ỌDẸ FÚN ÀṢEYẸ* TÍ ADÉBÓYÈ BABALỌLÁ KỌ

ÒKÉWÁNDÉ Olúwọlé Tẹ́wọ́gboyè,
Ẹ̀ka- Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀-Èdá-èdè Àti Àwọn Èdè Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà
Yunifásitì Ìlọrin, Ìlọrin.
E-Mail Address: oluwoletewogboye@yahoo.com

Àṣamọ̀

*'Ẹ̀ta-òkò' tàbí 'àárò-méta' tí kìí dọbẹ̀ nù ni àmúyẹ òdiwọ̀n iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́-lítírẹ́ṣọ̀ jẹ́: akópa, kókó tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ àti èdè. Kò ṣeé ṣe láti ṣègbéléwọ̀n tàbí ṣàpèjúwe afọ̀ lái ṣe àwòmọ́ akópa àti kókó-ọ̀rọ̀ tí afọ̀ dá lé lórí; kódà, akópa àti kókó-ọ̀rọ̀ yóò nípa lórí èdè àmúlò àti àmúyẹ afọ̀ lápapọ̀. Ìpèníjà tí afọ̀ ní fún ìkẹ́ṣẹjárí ni: Ta ni aṣafọ̀ tàbí àwọn aṣafọ̀ jẹ́ sí ìṣòrí ẹ̀yà-afọ̀? àti àyè ìjẹyọ afọ̀, èyí tó ní í ṣe pẹ̀lú ipò tí aṣafọ̀ bá ara rẹ̀. Ohun tó ṣe pàtàkì fún afọ̀-ajẹmẹ́wì alohùn ni, láti lè ṣètọ́kasí ìṣẹ̀ré, ní àwòmọ́ pẹ̀lú òṣèré àti ìsàré. Lónà mìíràn, bí omi ati aró tí kò ṣeé yà nípa, ni akópa ati kókó inú afọ̀ jẹ́. Ìṣàpèjúwe akópa àti kókó-ọ̀rọ̀ inú **Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ** tí Adébóyè Babalọlá kọ yóò ràn wá lọ́wọ́ làti lè ṣàgbékalẹ̀ àwòmọ́-akópa àti kókó-ọ̀rọ̀ (àkóónú) ìjálá tó pegedé. A ṣàmúlò àwọn èdè fáyẹ̀wò tó níbàámu pẹ̀lú òdiwọ̀n ìtúpalẹ̀: ìtayọ; bẹ́ẹ̀ ni a ṣe àwòmọ́ ìjálá pẹ̀lú akópa kọ̀ọ̀kan àti gbogbo akópa lápapọ̀. Ó hàn gbangba pé, akópa ìjálá ní àwòmọ́ àmúyẹ ìkẹ́ṣẹjárí nípa ìjẹyọ èdè ìbílẹ̀ akópa, èyí tó máa ń ṣatọ́nà òdiwọ̀n ìmédèlò ìjálá; nígbà tí ìtayọ kókó-ọ̀rọ̀ inú ìjálá máa ń jẹ́ itayọ afọ̀ ajẹmóríkì àti orílẹ̀, ìjálá ajẹmáyẹyẹ onírúurú àti ìjálá ajẹmọ́-ìrèmọ̀jẹ́ (ìjálá awo- ẹgbẹ́- ọdẹ).*

ÌFÁÁRÀ

Ìjálá jẹ́ ewì alohùn káríayé ilẹ̀ Yorùbá tó so mọ́ iṣẹ́ àti aṣafọ̀ ajẹmógùn-ún. Iṣẹ́ Babalọlá (1966) "The content and form of Yorùbá ìjálá" (àkoónú àti ìrísí ìjálá Yorùbá) ló ṣíṣọ kúrò lójú eégún pàtàkì ìjálá láwùjọ Yorùbá àti lágbàáyé. 'Ìràwọ̀ ọ̀sán' tí gbogbo àgbà ń pé wò nisẹ́ rẹ̀ jẹ́ nípa ìjálá. Nínú iṣẹ́ yìí ni a ti mọ pàtàkì,

ohùn àti ètò àdámọ́ fún ìdámọ̀ ìjálá. Rírì iṣẹ́ yìí ló mú kí Ọlágbèmí (2000) rí iṣẹ́ Babalọlá (1966) bí "Ògúnlànà aṣàtúpalẹ̀ lítírẹ́ṣọ̀ alohùn Yorùbá"

Iṣẹ́ Àjàdí (1997) ṣàgbéyẹ̀wò ewì "ìbà Olódùmarè" tí Ògúndáre Fọ́yánmu fi ìjálá ké. Ó jẹ́ ká mọ̀ pé, ìjálá máa ń ṣàfihàn Ògún àṣà, ìtàn, èrò-báyéṣerí àti ìwòye Yorùbá nípa ayé. Ó fihàn pé, ẹ̀wà ajẹmọ́-ẹ̀dá-èdè àti ẹ̀wà-èdè-aláwòmọ́-lítírẹ́ṣọ̀ kún inú afọ̀ náà fọ́fọ́. Ọlájubù (1981) ti ṣaájú wòye pé, bákan náà ni àkoónú gbogbo ewì alohùn Yorùbá, ohùn àti ọ̀nà ìṣafọ̀ ló yàtọ̀. Lónì-ín, ọ̀pá ẹ̀bìtì ìwúlò ìjálá ti ré síwájú. Àkoónú ìjálá ti gbàrà mìíràn dá; kò sí ohun tí àkóónú ìjálá kò lè dá lé lórí. Bí àpẹẹrẹ, ewì Ogúndáre Fọ́yánmu "ọmọ", àkóónú àti ìhun rẹ̀ yàtọ̀ gbedegbe sí àkóónú ewì alohùn Yorùbá lápapọ̀; bẹ́ẹ̀ sì ni, ìjálá ewì Àlàbí Ògúndépò "Kọ̀rú ọmọ Ọ̀pálábà" àti "èwe ìwòyí". 'Ìkìlọ̀' ni pàtàkì àkoónú àwọn ìjálá ewì wọ̀nyí dálé lórí.

Finnegan (1977) ní, ìpegedé ewì alohùn dá lórí ìjáfáfá aṣafọ̀, afọ̀ ni yóò ṣèdarí àdámọ̀ ìṣọwọ́ afọ̀. Kò sí àní-àní pé, jíjọ ni yóò jọ, Òṣùpá ò lè dàbí Òòrùn. Bí ìjọra ṣe wà láàárin àwọn èyà ewì alohùn Yorùbá tó, ìyàtọ̀ ìsọwọ́ wà láàárin wọn. Babalọlá (1982) ṣàgbéyẹ̀wò ìwọ́hùn nípele-ǹ-pele: ìkíni lóhùn-ẹnu, ìlò àfiwé (tàárà àti ẹlẹ́lọ́ọ́), ilò àwòrán-inú, àfidípò, àwítúnwí àti ìyàtọ̀ ní òpin ẹ̀ka-ìwọ́hùn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ inú ìjálá. Àwòmọ́ asùnjálá nisẹ́ Àjùwọ̀n (1981b) dá lé lórí. Nínú iṣẹ́ yìí ló ti ṣàgbéyẹ̀wò kíkójọ àti ìṣèré aṣafọ̀ ìjálá; nígbà tí Ajíbádé (2012) ṣàgbéyẹ̀wò ewì ìjálá pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ẹnu pẹ̀lú àgbálọgbábọ̀ pé àwọn aṣafọ̀ ní oríṣìíríṣìí ète ìṣọwọ́lò-èdè láti mú kí ìṣèré wọn yéni yékéyéké.

Àwòmọ́ ìpegedé ìjálá nisẹ́ Babalọlá (1981) dálé lórí. Ó ní ìgbéjáde ohùn ìjálá gbọ́dọ̀ jé ìránmú. Babalọlá (1981, o. i. 15) ní "imú là á rán sùnjálá". Ìjáfáfá ìṣàmúlò àbùdá ìránmú asùnjálá yìí ni yóò mú wa ṣòdiwọ̀n ohùn ìjálá. Asùnjálá tó bá pegedé ìṣàmúlò ohùn ìjálá là ń ṣàpèjúwe bí "onijàálá olóhùn dídùn" (Babalọlá 1981, o. i. 15). Ohùn ìránmú yìí gbọ́dọ̀ sún mọ́ ohùn orin, lái jẹ́ bẹ́ẹ̀, ìjálá rẹ̀ kò níí dùn. Àṣomọ́ orin pẹ̀lú ohùn ìjálá yìí ni afọ̀ *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ* jẹ́. 'Orin Ọdẹ' nìlànà ìṣàgbékalẹ̀ afọ̀ ìjálá yìí. Ilésanmí (2004, o. i. 50) pín ọ̀nà ìgbàṣafọ̀ sí méta: ilànà ọ̀rọ̀-ẹnu,

ìlànà ìsàré àti ìlànà orin. Ìjálá a máa ṣàmúlò àpapọ̀ ìlànà ìsàré àti orin fún ìpegédé. Níwọ̀n ìgbà tí ìgbédè àti ìmèdè èdè Yorùbá ti jẹ́ alámì, ìṣàmúlò ìfàgùn, gígé-ohùn pé-pè-pé, gbígbọn tán-án ná ọ̀nà-ọ̀fun láti mú kí ohùn gbọ̀n rì-rì ni à ń ṣe fún ohùn ìsàlẹ̀, ti àárin àti ohùn òkè láti mú adùn ìjálá tó pegedé jáde. Àkíyèsí yìí ni Ilésanmí (2004, o. i. 50) ṣe pé

> Heightened pitch and the freedom or liberty to prolong any vowel or any length to the idiosyncrasies of the chanting artist
>
> Ìgbóhùnsókè-sódò àti òmìnira àti ṣe ìfàgùn fáwẹ̀ẹ̀lì tàbí sílébù jẹ́ ti ìmọ̀ tàbí làákàyè Ọ̀kọ̀rin.

Kíkọ̀ àti sísun ìjálá bẹ̀rẹ̀ láti ìfetísílẹ̀-gbọ̀ sísùnjálá, sísínjẹ ìjàlá, sísùnjàálá ajẹmégbè-orin-ìjálá, títí dé ìṣàgbékalẹ̀ ìṣẹ̀dá ìjálá titun. Agbẹnusọ Ògún tí í ṣe olùdásílẹ̀ ìjálá ni gbogbo asùnjálá (Ọdẹ) jẹ́ (Babalọlá, 1981 o. i. 8).

ÌTAYỌ BÍ ÌLÀNÀ ÌṢỌWỌ́LÒ-ÈDÈ.

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí ìlànà ọ̀nà ìṣọwọ́lò-èdè yìí. Lára wọn ni Halliday àti Hasan (1976), De Beangrade àti Dressler (1981) àti Awóyalé (1990). Kò ṣeé ṣe fún oníṣẹ́-ọ̀nà-aláwòmọ́-lítírẹ́ṣọ̀ láti pín iṣẹ́ fún akópa, ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ìrírí inú afọ̀ bákan náà. Ìwòye yìí ni Callow (1974, o. i. 49) wò pé

> A story in which every character was equally significant can hardly be imagined. Even the simplest story has at least a central character is more important than others and certain events likewise…
>
> Bó ti wù kí ìtàn kéré mọ, kò ṣe é ṣe láti pínṣẹ́ fún akópa, ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ìrírí bákan náà. Ìtàn tó kéré jù lọ gbọ̀dọ̀ ní olú-akópa èyí tó ṣe pàtàkì ju àwọn yòókù bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ sì ni ìṣẹ̀lẹ̀ pẹ̀lú…

A lè ṣe ìgbéléwọ̀n bí àwọn èròjà tí òǹkọ̀wé lò ṣe ṣe pàtàkì sí, láti mọ pàtàkì ọ̀kọ̀ọ̀kan síra wọn nínú afọ̀ nítorí pé, ayé kò tọ́ lọ bí ọ̀pá ibọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn èròjà inú afọ̀ kò dọ́gba. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn àbùdá ló lè fi ọ̀diwọ̀n ìtayọ hàn nínú afọ̀. Ìjẹyọléra pẹ̀lú

ìwàléra irú àwọn àbùdá wọ̀nyí ni yóò ràn wá lọ́wọ́ láti mọ ohun tí òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ ń fèdè fọ̀ lénà. Lára irú àwọn àbùdá wọ̀nyí ni ìtújáde ọ̀rọ̀ tó ki tó sì dí; nítorí, kò níí sí àyè fún ìranù. Àwọn ọ̀diwọ̀n tó tún ṣe pàtàkì fún ọ̀diwọ̀n ìtayọ ni àwílé àti ìtanilólobó. Halliday (1970) rí ìtayọ bí ìfojú-inú wo ìjẹyọ ẹ̀dá-èdè; nínú èyí tí àwọn àbùdá ẹ̀dá-èdè bẹ́ẹ̀ yóò ṣèrànwọ́ láti rí ìṣọwọ́ irú afọ̀ bẹ́ẹ̀.

Ìtayọ ní í ṣe pẹ̀lú bí ara kan lára ìhun ṣe ru sókè tàbí fẹ̀ ju ara ìhun yòókù lọ. A gbọdọ̀ rí iṣẹ́ lítírẹ́ṣọ̀ bí ìlà kan ṣoṣo. Ṣé ìlà yìí tọ́ sangbọndan ni tàbí ó wọ́? Bí a bá wo àwọn àmúlò ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ìrírí akópa àti àwọn ẹ̀hun wúnrẹ̀n-èdè, a ó rí i pé, kò lè tọ́ lọ bákan náà. Ibi tí ìgbérasókè ti jẹyọ ni ìruke. A gbọdọ̀ ṣe ìfiwéra àwọn iké wọ̀nyí ní fífẹ̀ àti gíga, bí a ó bá fi àwòrán gíráàfù gbe àlàyé wa lẹ́ṣẹ̀.

Ìṣọwọ́ afọ̀ ní í ṣe pẹ̀lú òté ìgbà ìjẹyọ; kì í ṣe nípa ìjẹyọléra nìkan, ṣùgbọ́n, ipa irú ìjẹyọléra àti ìwàléra bẹ́ẹ̀. Àlàyé atọ́ka àpótí ajúwe ṣe pàtàkì fún àlàyé ìtayọ. De Beangrande àti Dressler (1981, o. i. 41) ní "statistical trends too provide us with many style markers" "Àlàyé ìlànà ìṣàpèjúwe oníṇọ́ńbà máa ń jẹ́ àfikún àlàyé atọ́ka ìṣọwọ́ afọ̀". Lójú Geoffery àti Short (1981, o. i. 47) a nílò ìlànà ìmọ̀ ìṣirò láti ṣàgbékalẹ̀ àlàyé ìtayọ afọ̀, nípa ìjẹyọ ẹ̀dá-èdè. Wọ́n ní .

> The more a critic wishes to substantiate what he says about style, the more he will need to point to the Linguistic evidence of texts; and Linguistic evidence to be firm, must be couched in terms of numerical frequencies…a rough indication of frequencies is often what is needed enough to suggest why we should accept the analyst's assertion that some feature is prominent in the text.
>
> Bí lámèétọ́ ti ń gbìyànjú láti fidí ohun tó ń sọ múlẹ̀ nípa ìṣọwọ́ afọ̀, bẹ́ẹ̀ ni ó ní láti fidí ẹ̀rí ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè tó rinlẹ̀ múlẹ̀; èyí tó ní í ṣe pẹ̀lú ìjẹyọléra oníṇọ́ńbà …pàṣípàárọ̀ atọ́ka ìjẹyọléra ló ṣe pàtàkì kí atótónu àlàyé rẹ̀ lórí ìtayọ àwọn àbùdá inú afọ̀ kan tó ṣètẹ́wọ́gbà.

Èyí fihàn pé, bí àlàyé ìlànà ìṣirò bá ti jẹ́ àgbékalẹ̀ sí ni àlàyé itayọ afọ̀ yóò ṣe fidí múlẹ̀ tó nípa àbùdá ìṣọwọ́ afọ̀. Ìfàyègbà ni yóò ṣàfihàn àyè tì òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ fi gba ìṣẹ̀lẹ̀, ìrírí tàbí akópa kan sí òmíràn. A gbọ́dọ̀ wo ibi àti ìgbà-ìjẹyọ irú òdiwọ̀n béẹ̀ ní àwòjinlẹ̀. Ìtẹnumọ́ náà jẹ́ òdiwọ̀n pàtàkì láti ṣòdiwọ̀n afọ̀. Yorùbá ní, ìṣu atẹnumọ́ràn kì í jóná. Ohun tí aṣafọ̀ tàbí òǹkọ̀wé ń rán lẹ́nu, bí kò bá dùn ún, a sì jẹ́ pé ó ń dùn mọ́ ọn. Àwọn òdiwọ̀n itayọ mìíràn ni: àwítúnwí, ìtúnjẹyọ àti ìgbéyọsíwájú àti séyìn.

Ìjẹyọ òdiwọ̀n afọ̀ lábẹ́ ìṣọ̀rí ìbátan kan náà ni a lè fi ṣàpèjúwe afọ̀ Ayọ̀dàbọ̀ (1979). Kíka ìgbà ìjẹyọ òdiwọ̀n nínú afọ̀ àti ibi pàtàkì irú ìjẹyọ béẹ̀ ṣé kókó fún òdiwọ̀n itayọ Geoffery àti Short (1981). Èwè, ó ṣéé ṣe kí òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ ṣàmúlò díẹ̀ tàbí púpọ̀ lára àwọn òdiwọ̀n wọ̀nyí. Àwọn èyí tó ṣe kókó nínú afọ̀ ló yẹ láti ṣàgbéyẹ̀wò.

ÌTAYỌ KÓKÓ-ỌRỌ̀ INÚ *ORIN ỌDẸ FÚN ÀṢEYẸ*

Afọ̀ kọ̀ọ̀kan ló máa ń ní ipa àti ìwúlò rẹ̀. Ìṣẹ́ tí àkóónú afọ̀ ń ṣe gbọdọ̀ bá ìlànà afọ̀ mu. Ìdí nìyí tí Ilésanmí (2004, o. i. 98) fi ní:

> Each specific Yorùbá genre has a specific function; thus in assessing the appropriateness of a genre or repertoire, it should be done within its appropriate functional context
>
> Ọkọ̀ọ̀kan èyà afọ̀ Yorùbá ló ní iṣẹ́ kan gbòógì tó ń ṣe; nípa ìgbéléwọ̀n ìtọsúnà èyà-afọ̀, èyí gbọdọ̀ wáyé nípaṣẹ̀ ìtọsúnà iṣẹ́ ọ̀gangan-ipò

Àgbéyẹ̀wò àwọn kókó-ọ̀rọ̀ inú ìjálá *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ* yóò ràn wá lọ́wọ́ láti le mọ àkóónú tí ìjálá máa ń ní. Lọ́nà mìíràn, ìjálá aré ọdẹ yóò jẹ́ ká le ṣègbéléwọ̀n rẹ̀ bí èyà-afọ̀.

Iṣẹ́ onímọ̀-ìṣọwọ́lò-èdè ni láti lè tún iṣẹ́ aláwòmọ́-lítírésọ̀ tò, yàtọ̀ sí bí òǹkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ ṣe gbé e lé wa lọ́wọ́; yálà, kókó, ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ìrírí. Méta ni a pín ìjẹyọ kókó-ọ̀rọ̀ inú afọ̀ yìí sí: ìjálá ajẹmóríkì, ìjálá ajẹmáyẹyẹ àti ìjálá ajẹmọ́rèmọ̀jé tàbí ìṣípà-ọdẹ. Nínú kókó méta tí afọ̀ ìjálá yìí dá lé, ìjálá ajẹmóríkì ló gba ìtayọ:

(oríkì Olódùmarè, oríkì òrìṣà Ògún, oríkì ọlọ́danni, oríkì-orílẹ̀, oríkì ẹranko, oríkì igi, oríkì ẹyẹ àti oríkì òúnjẹ). Kìkìdá tàbí ògidì oríkì nìṣọ̀rí kókó-ọ̀rọ̀ yìí dá lé. Ìjálá méjì ni a fi ṣọrí isọ̀rí kókó-ọ̀rọ̀ yìí: 'ìjálá lọ́jọ́ ìgbẹ́ Ògún' àti 'ìjálá orin ọdẹ fún àríyá'. Oníruurú ìjálá ajẹmóríkì wọ̀nyí fihàn bí afọ̀ ajẹmọ́jàálá ṣe fẹ̀jú, tó kẹ́nú tó sì jìnlẹ̀ bí èyà-afọ̀ alohùn Yorùbá. Nínú ọgọ̀ọ̀rọ̀ àwọn oríkì wọ̀nyí, oríkì ọlọ́danni ló gba ìtayọ jù lọ. Lábẹ́ ìjẹyọ irúfẹ́ oríkì yìí ni a ti rí oríkì Babárìnlọ, o. i. 49, Ìlà 56-119, oríkì Adélékè, o. i. 156 àti 157, ìlà 273-289, oríkì Ògúnwálé, o. i. 172 àti 173 ìlà 735-840, oríkì Akínlàwọ́n, o. i. 174 ìlà 849-864, oríkì Ògúnmọ́dẹ́dé, o. i. 176 àti 177 ìlà 865-881, oríkì Fábùnmi, o. i. 178 ìlà 910-925 àti oríkì Ṣèédù Ọlábérinjọ, o. i. 180 ìlà 976-1004. Ìjẹyọ àwọn oríkì wọ̀nyí ṣàfihàn ìrísí, ìran, iṣẹ́, ihùwàsí àti ẹbí òun ìbátan wọn. Bí àpẹẹrẹ, oríkì Ṣèédù Ọlábérinjọ, èyí tó jẹyọ lójú-ìwé 180 ìlà 976 -1004:

> Mo rí'bà, kí'bà mi kó máa ṣẹ:
> Ṣèédù Ọlábérinjọ.
> Ọkànbádé Akígbemárù-bí-àgbà-ọ̀fàfà.
> Ijà inú tógò baba Ògúnwálé,
> baba Ògúnwálé nìkan kọ́,
> baba Ògúndáhùnsi ni
> Ọkùnrin gbọ̀ngbọ̀ngbọ̀n bí ọjọ́ tí-kanrí,
> Ọkùnrin gbọ̀ngbọ̀ngbọ̀n bí ẹni f'ìbọn tì;
> ...ìjà ìjà ìdùbúlẹ̀ n ii f ii-gb'ara 'ẹ̀ sílẹ̀.
> Ọmọ Oníkòyí; kí o gbàá l'ẹ́nu mi, ko sọ ọ́ dorin.

Nípasẹ̀ àyọlò oríkì Ṣèédù Ọlábérinjọ yìí, a mọ ìrísí ẹni tí a ń fijálá yìí perí (Ṣèédù Ọlábérinjọ) bí ẹni sísanra tó sì ṣígbọnlẹ̀; ẹni tí yóò dá a lẹ́kẹ yóò múra, béẹ̀ gégé ni a mọ àwọn ọmọ tó bí àti orílẹ̀ rẹ̀ pẹ̀lú.

A rí ìjẹyọ ìtayọ oríkì Ẹtu lábẹ́ oríkì ẹranko (o. i. 137 àti 138 ìlà 1-43):

> Ẹtu, ọlańgbadé ẹtu òtòǹpòrò l'égàn,
> alágbéré ò kú, alágbéré a kú sóko?
> Ẹtu tí ń dán bí ẹ̀lọ̀.
> Ẹtu gbéré bí ẹni à ń nù.
> Lájìǹbú aláyàagbẹ̀du kooro ọpọ́n idẹ.

Ẹtu olúkójọ, Fàlàkẹ, aríàlàtẹ́sùn,
Káńgbọ́n-l'àgbéré amèrùwà.
Abiran í-tó'wò ẹrú, abẹ́sẹ̀ í-tó'wò-ìwọ̀fà,
Abìjà-ǹ-já-palááárù-tan-tan-tan.
Abawọ-í-tó-baálẹ́ í sùn tọmọtọmọ
Ẹtu tí ọmọ ọdẹ ń dárí kàn ní'jù,...

Ó hàn nínú àyọlò oríkì Ẹtu òkè yìí pé ó fẹ́ràn fáàrí ṣíṣe; ó fẹ́ràn rínrìn láàlà-oko; bẹ́ẹ̀ ni awọ rẹ̀ wúlò púpọ̀. Ẹran ajé ni í ṣe pẹ̀lú.

Nípasẹ̀ oríkì Ògún tó jẹyọ lójú-ìwé 159, ìlà 358-489 ni a fi mọ̀ pé, "Ìrè kì í ṣe ilé Ògún, ẹmu l'Ògún yà mu ní 'rè." Bẹ́ẹ̀ ni a mọ̀ pé, Ṣakí nìlú Ògún. A nímọ̀ nípa àwọn ẹran ìbọ Ògún bákan náà: Ògún onírá: ẹran ajá, Ògún onírè: ẹran-àgbò. Àlòpọ̀ àwọn ẹran ìrúbọ Ògún wọ̀nyí ní í ṣe pẹ̀lú ilú tí irúnmọ̀lẹ̀ yìí gbé nígbà ayé rẹ̀. Irú àlòpọ̀ afọ̀ yìí ni a rí nínú afọ̀ ajẹmọ́we pé 'ẹni tó bá mojúbọ Ògún là ń jẹ́ kó yanbì ní'rè'.

Kókó-ọ̀rọ̀ tó gba ìtayọ ṣíkejì ni ìjálá ajẹmáyẹyẹ. Lábẹ́ ìsọ̀rí afọ̀ yìí ni a ti rí ìjálá ní'bi àsè iyọ̀ara, ìjálá níbi òkú ṣíṣe, ìjálá ní'bi ilé ṣíṣí, ìjálá ní'bi àsè ìgbéyàwó, ìjálá ní'bi ìkómọ́jáde, ìjálá ní'bi ìwúyè, ìjálá ní'bi èésú dídá àti àjọ kíkó àti ìjálá ní'bi ìkínikáàbọ̀. Èyí jẹyọ lọ́nà ìwúre, síṣàdúrà àti ìpè. Bí àpẹẹrẹ, a rí ìjẹyọ ìjálá yìí ní'bi ìjálá iyọ̀ara ní ojú-ìwé 1 àti 2 ìlà 17-27

Ikúdòfo ò ní í-sọ 'lé rẹ d'òfo,
àrùn ò ní í-sọ 'lé rẹ d'òfo,
Ògún yóò máa gbè ọ́
B'ó ti gb'Akálà ilé Ìdó,
b'ó ti gb'Akalà ọmọ ọ̀wẹ̀,
b'ó ti gbe'Gbópă; ọmọ
abọ̀gúnbọ̀ṣàwele, àti
Dìgbòlùwọ́n ọdẹ Ìníṣà
Ọ̀yìnyín Ògún kò ṣé í-rí,
Ògún ò ní í-jẹ́ ẹ r'ọ́yìnyín òun...

Àdúrà pẹ̀lú ìtọ́kasí Ògún tó jẹ́ òrìṣà aṣagbátẹrù ìjálá, 'Ikú' àti 'àrùn' ni ìpè tí a ṣe nínú ìjálá yìí láti yà wọ́n pẹ̀lú wọn; nítorí awóléọlá, wóléọlà ni a mọ̀ wọ́n mọ̀. Àyọlò yìí ṣètọ́kasí àwọn tí

Ògún ti gbè ṣaájú: Akálà, Gbópă àti Dìgbòlùwọ́n. Ayẹyẹ ìmúnúdùn, ìmóríwú àti ìmárayá ni pàtàkì ìjálá yìí jẹ́.

Kókó-ọ̀rọ̀ kẹta ni ìjálá ajẹmọ́-ìrèmọ̀jé (ìṣípà-ọdẹ). Ìjẹyọ ìsọ̀rí afọ̀ yìí jẹ́ ti awo ẹgbẹ́-ọ́dẹ; kì í ṣe ìjálá akópa tawo-tọ̀gbẹ̀rì. Ìjálá yìí wà fún ọmọ ẹgbẹ́ ọdẹ tó rèwàlẹ̀-àsà. Ìjálá orò-ìkẹyìn ni ìsọ̀rí ìjálá yìí jẹ́. 'Ògúndìjí' ni a fi ìjálá ìrèmọ̀jé yìí sọ́rí nínú *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*. Lára àkóónú ìsọ̀rí ìjálá yìí ni sísàyẹ̀wò iṣẹ́ ọdẹ (Ògúndìjí) nígbà tó wà láyé, ìran rẹ̀, oríkì rẹ̀, ìwà tàbí ihùwàsí rẹ̀, ìṣàfihàn àwọn ohun-èlò ọdẹ àti orílẹ̀ ọdẹ. Bí àpẹẹrẹ, a lè ṣètọ́kasí oríkì àti orílẹ̀ Ògúndìjí tí a fi ìjálá yìí perí ní ojú-ìwé131 àti 132:


...ojú ilé akin rè é, Ògúndìjí Ọyáníyì Apamọ̀ṣàsè
Ọyáníyì Apamọ̀ṣàsè
tí ng ba ńlọ'lé wọn, ìyálóde ibẹ̀ n'lé wọn
ní Ìwó Mère Aṣénibuomi Atẹ́sẹ́roro,
Ìwó modò m'ọbà
ojú l'ó pọ́n baba Olúgbọ́n,
ni ó nf'apó gbárí;
ojú l'ó pọ́n baba mi, Ẹ̀là Òjé,
l'ó fi Erinlẹ̀ sọfà;
ojú l'ó pọ́n baba Olúwòó,
l'ó bomi ọbà mu.
Ìwó kì í s'ọmọ odò ọbà
Olúwòó b'omi odò ọbà mu ni.
ará Olúpọ̀nnà kọ́ l'ó l'ọ̀ṣun, ọmọ l'ó fún wọn.
Ìjẹ̀ṣà Àbẹ́ní gbógungbórò l'ó lọ̀ṣun...

A mọ̀ nípa oríkì àti orílẹ̀ Ìwó; èyí tó jẹ́ ilú Ògúndìjí tí a fìjálá yìí sọ́rí. Nípasẹ̀ ìjálá yìí ni a fi mọ̀ pé, Ìwó kọ́ ló lodò ọbà; bí ó tilẹ̀ ti dàṣà pé 'Ìwó ọmọ olódò ọbà.' Èyí ṣàfihàn ìjálá bí 'àlùmọ́ọ́nì ìtàn ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá' àti àwọn asùnjálá bí òpìtàn, ọ̀mọ̀tàn àti arọ́tàn.

Ìjẹyọ kókó-ọ̀rọ̀ inú *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*:

S/N	Kókó-ọ̀rọ̀	Iye-Gbólóhùn	Iye-ojú-ìwé
1.	Ìjálá ajẹmóríkí	2, 232	80-111 &136-183 (88)
2.	Ìjálá adálórí-ayẹyẹ (taṣo-tọ̀gbẹ̀rì)	1, 516	1-73 (73)
3.	Ìjálá ajẹmọ́rèmọ̀jé/ìṣípà-ọdẹ (awo: ọdẹ)	487	117-136 (22)
	Àròpọ̀	**4, 335**	**183**

Ní àfikún, àfihàn atọ́ka onílànà ìṣirò pái ṣaàtì tó ṣàfihàn iye ìgbà-ìjẹyọ àti ìfàyègbà kókó-ọ̀rọ̀ ni a ṣàfihàn nísàlẹ̀ yìí:



Akíyèsí:

(a) Àropọ̀ ìdá ọgọ́rùn-ún = 100
(b) Àròpọ̀ dìgírí = 360
(c) Àròpọ̀ Ojú- ìwé = 183
(d) Àròpọ̀ Gbólóhùn = 4,335

ÀWÒRÁN ATỌ́KA PÁÍ-ṢAÀTÌ ÌFÀYÈGBÀ ÀTI ÌGBÀ ÌJẸYỌ KÓKÓ-ỌRỌ̀ INÚ *ORIN ỌDẸ FÚN ÀṢEYẸ*

Ó hàn nínú àwòrán atọ́ka yìí pé ìjálá ajẹmóríkì ni ó gba ìtayọ nípa àyè àti ìjẹyọ nínú *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*; èyí tó ṣàfihàn àfojúrí pé, kò sí bí a ṣe lè ṣebòlò, kó mọ́ rùngbẹ́, ni ìjálá pẹ̀lú oríkì. Ojú-ìwé méjì-dín-láàádọ́rùn-ún (88), tó dúró fún ìdá méjì-dín-láàádọ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (48%); èyí tó dúró fún ìdá àádọ́sàn-án-lé- méta nílànà dìgírí (173^0). Ìjálá ajẹmáyẹyẹ gba ojú-ìwé métà-lé-láàádọ́rin (73), tó dúró fún ìdá ogójì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (40%); èyí tó dúró fún ìdá ogóje-lé-mẹ́rin nílànà dìgírí (144^0). Ìjálá ajẹmọ́rèmọ̀jé ló tayọ ṣìkẹta pẹ̀lú ojú-ìwé méjì-lé-lógún (22), tó dúró fún ìdá méjìlá nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (12%); èyí tó dúró fún ìdá méjì-lé-lógójì (42^0) nílànà dìgírí. Mo kò ó a máa lápèjúwe, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, oríkì ló tayọ nínú afọ̀ ajẹmọ́jàálá, síbẹ̀, a ti fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìjálá ajẹmóríkì àti orílẹ̀ ló máa ń tayọ.

ÌTAYỌ AKÓPA INÚ *ORIN ỌDẸ FÚN ÀṢEYẸ*

Akópa ni onkọ̀wé máa ń fèdè sí lẹ́nu láti gbé tàbí láti fi èró-ọkàn ònkọ̀wé tàbí aṣafọ̀ ráńṣẹ́ sáwùjọ. Gbogbo àwọn akópa inú afọ̀ ni wọ́n jẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ asùnjálá (ọdẹ). Ìlànà gbe-n-gbà ni afọ̀ náà gùn lé. Inú agbo ni ìṣèré àwọn asùnjálá ti wàyé. 'Ọkọrin' ni àfipè ti ònkọ̀wé fi ṣètọ́kasí gbogbo asùnjálá; nípa bẹ́ẹ̀, a kò lè tọ́kasí asùnjálá pẹ̀lù orúkọ àbísọ pọ́ńbélé. A gbìyàjú láti tọpinpin orísun díẹ̀ lára àwọn asùnjálá pẹ̀lú ìṣọwọ́ èdè wọn. Ọ̀nà mẹ́ta ni a lè pín ìjẹyọ àwọn akópa sí nínú iṣẹ́ aláwòmọ́-lítírẹ́ṣọ̀: olú-akópa, akópa amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ àti akópa amágbokún. Olú-akópa jẹ́ orí. Akópa amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ jẹ́ amúpé; nígbà tí akópa amágbokún jẹ́ àfikún. Láìsí Tàgíìrì, awọ ò hu ni olú-akópa máa ń jẹ́. Kò sí lágbo, agbo ò kún; kò sí lájọ, àjọ ò jọ ni. Ipa àti ipò rẹ̀ ló máa ń rinlẹ̀ jù lọ.

Kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ kú isó pin lọ́rọ̀ olú-akópa, bí ó bá ti kú, eré kú (parí tàbí kí ó pin) nìyẹn. Kò sí kòmóòkun kankan tí a lè fi ṣòdiwọ̀n tàbí tí a lè fi ṣègbéléwọ̀n afọ̀ tí olú-akópa kò ní jẹ́ òté fún. Akópa kan ṣoṣo lèyí sábà máa ń jẹ́. Àwọn akópa amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ jẹ́ 'mọ́- jẹ́ẹ́-ó-bàjẹ́', àwọn ni akópa èjìká, tí kò jẹ́ kí ẹ̀wù bọ́ lórùn. Láìsí àwọn akópa wọ̀nyí, àṣeyọrí jìnnà sí olú-akópa papàá; ṣé awo nií gbáwo nígbọ̀wọ́. Ìsọ̀rí akópa yìí, akópa tàbí àwọn akópa lè jẹ́ méjì sókè, èyí dá lórí afọ̀. Díẹ̀ ni t'Àlàbá nínú ọ̀rọ̀ ìbejì ni àwọn tàbí akópa amágbokún jẹ́ nínú afọ̀; nítorí, bí a bá mú wọn kúrò nínú afọ̀ 'àgunlá, àguntẹ̀tẹ̀' ni; kò lè ṣàkóbá kankan fùn ìkẹ́ṣẹjárí afọ̀. Àràkún laṣọ Gbági lọ́rọ̀ àwọn akópa amágbokún, àfikún ni wọ́n.


Gbogbo àwọn akópa (asùnjálá) ló ní ìsopọ̀ kan náà: iṣẹ́-ọdẹ. Lọ́nà mìíràn, ọkùnrin ni gbogbo àwọn akópa jẹ́, kò sí obìnrin kankan nínú wọn. Àwòjinlẹ̀ afọ̀ yìí fi hàn pé, a fàyè gba akópa kan ju òmíràn lọ nínú ìsàré afọ̀ *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*. Nígbà mìíran, a ṣàmúlò 'ọkọrin', nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀ 'ọdẹ' gégé bí ìtọ́kasí àfipè asùnjálá; níwọ̀n ìgbà tí orúkọ àbísọ akópa ti sá wa lójà.

Ìlànà ìṣèré ni a gbé afọ̀ *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ* gbà; nítorí náà, ìpagbo ìṣèré, òǹwòran, ìfojú-fara-sọ́rọ̀ jẹ́ àwòmọ́ ìbójú-ayé-mu *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ* bí afọ̀ tó kógo ìsàré alohùn já. Nípasẹ̀ ipa àti ipò tí akópa kó, ni a fi tọpinpin ìṣeéṣe ìlú tàbí agbègbè tí àwọn akópa ti wá. Akópa méwàá ni àpapọ̀ iye àwọn akópa inú afọ̀ yìí. Ìjẹ́yọ àti ìfàyègbà gbólóhùn àti ojú-ìwé ni a ṣàgbékalẹ̀ báyìí:

S/N	Akópa	Ìgbà-ìjẹ́yọ	Iye-gbólóhùn	Iye-ojú-ìwé
1	1	13	1, 755	77
2	2	10	985	45
3	3	7	832	23
4	4	4	184	10
5	5	3	90	6
6	6	2	70	6
7	7	3	124	5
8	8	2	156	5

9	9	1	102	3
10	10	1	37	3
		46	**4, 335**	**183**

Ní àfikún, àfihàn atọ́ka onílànà ìṣirò pái ṣaàtì tó ṣàfihàn iye ìgbà-ìjẹ́yọ àti ìfàyègbà kókó-ọ̀rọ̀ ni a ṣàfihàn nísàlẹ̀ yìí



Àkíyèsí:
(a) Àròpọ̀ Akópa = 10
(b) Àròpọ̀ Iye ojú-ìwé = 183
(d) Àròpọ̀ ìdá ọgọ́rùn-ún = 100
(e) Àròpọ̀ ìdá dìgírí = 360

kọ́kọ́rọ́ Àmì:
* = iye ojú-ìwé
+ = ìgbà-ìjẹ́yọ
0 = dìgírí
% = ìdá-ọgọ́rùn-ún

ÀWÒRÁN ATỌ́KA PÁÍ-ṢAÀTÌ ÌFÀÀYÈGBÀ ÀTI ÌGBÀ ÌJẸYỌ AKÓPA INÚ *ORIN ỌDẸ FÚN ÀṢEYẸ.*

Nípasẹ̀ àwòrán atọ́ka òkè yìí, ó hàn dájú pé ojú-ìwé métà-dín-lọ́gọ́rin (77), èyí tó dúró fún ìdá méjìlélógójì ìdá ọgọ́rùn-ún (42%) pẹ̀lú ìdá àádọ́jọ-lé-kan (151^0) dìgírí ni a fi gba akópa àkọ́kọ́.

Iye ìgbà ìjẹyọ rẹ̀ sì jẹ́ mẹ́tàlá (13): èyí tó mú kó gba ìtayọ akópa jù lọ nínú afọ̀ yìí. Akópa kejì gba àyè ojú-ìwé márùn-dín-láàádọ́ta (45) tó dúró fún ìdá mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n (25%) ní ìdá ọgọ́rùn-ún, pẹ̀lú ìdá ọ̀kàndínláàádọ́rùn-ún (89^0) dìgírí. Ìgbà mẹ́wàá ló sì jẹyọ nínú afọ̀. Akópa kẹta ni a fi ojú-ìwé mẹ́tàlélógún (23) tó dúró fún ìdá mẹ́tàlá (13%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún; tó dúró fún ìdá mẹ́rìnlélógójì nílànà dìgírí (44^0). Ìgbà ìjẹyọ rẹ̀ sì jẹ́ méje (7). Akópa kẹrin gba ojú-ìwé mẹ́wàá (10), tó dúró fún ìdá márùn-ún nínú ọgọ́rùn-ún (5%); pẹ̀lú ìdá ogún nílànà dìgírí (20^0). Ìgbà mẹ́rin (4) ló sì jẹyọ nínú afọ̀. Akópa kaàrún-ún gba ojú-ìwé mẹ́fà (6) tó dúró fún ìdá méta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (3%) èyí tó dúró fún ìdá dìgírí méjìlá (12^0). Ìgbà méta ló sì jẹyọ nínú afọ̀. Akópa kẹfà gba ojú-ìwé mẹ́fà (6) tó dúró fún ìdá méta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (3%) èyí tó dúró fún ìdá méjìlá nínú ìdá dìgírí (12^0). Ìgbà méjì ló sì jẹyọ. Akópa keje gba ojú-ìwé márùn-ún (5) tó dúró fún ìdá méta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (3%) èyí tó dúró fún ìdá mẹ́wàá nínú ìdá dìgírí mẹ́wàá (10^0). Ìgbà méta ló sì jẹyọ. Akópa kẹjọ gba ojú-ìwé márùn-ún (5) tó dúró fún ìdá méta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (3%) èyí tó dúró fún ìdá mẹ́wàá nínú ìdá dìgírí (10^0). Ìgbà méjì ló sì jẹyọ. Akópa kẹsàn-án gba ojú-ìwé méta (3) tó dúró fún ìdá méjì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (2%), èyí tó dúró fún ìdá mẹ́fà nínú ìdá dìgírí (6^0). Ìgbà kan péré ló sì jẹyọ. Bákan náà sì ni akópa kẹsàn-án tí òun náà gba ojú-ìwé méta (3) tó dúró fún ìdá méjì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (2%) èyí tó dúró fún ìdá mẹ́fà nínú ìdá dìgírí méjìlá (6^0). Ìgbà kan péré ló sì jẹyọ.

Ìpín méjì péré ni a lè pín àwọn akópa inú *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ* sí: olú-akópa àti akópa amúgbálẹ́gbẹ́ẹ́. Lọ́nà mìíràn, kò sí akópa amágbokún nínú àwọn asùnjálá inú *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*; nítorí pé, kò sí akópa tí a lè ṣàmúkúrò ipa àti ipò rẹ̀ nínú afọ̀ tí afọ̀ náà yóò sì tún wà lódidi, kódà; àwọn akópa tó jẹyọ nígbà kan ṣoṣo, ìfàyègbà tí a fún aṣafọ̀ kò ṣeé fojú rénà rárá.

A lè tọpinpin orísun tàbí ibi agbègbè tí àwọn asùnjálá ti wá pẹ̀lú àmúlò èdè ìjálá wọn. Nípasẹ̀ ìmédèlò aṣafọ̀, a lè ṣètọ́kasí aṣafọ̀ (asùnjálá) inú *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*. Ìwòye yìí ni Ilésanmí (2004, o. i. 99) wò, tó fi ní:

> The pride of an artist is his competent manipulation of language and or register. No matter how knowledgeable an artist may be he has to use his language competence as a vehicle for projecting his idea.
>
> Ohun àmúyangàn ló jẹ́ fún oníṣẹ́-ọnà láti fi ìmèdè rẹ̀ tàbí èdè-àmúlò hàn nínú afọ̀. Kò sí bí oníṣẹ́-ọnà ṣe lè nímọ̀ tó ó gbọdọ̀ ṣàmúlò ìmèdè rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹṣin-àfiwé ìgbérò rẹ̀ kalẹ̀.

Nínú *Orin Ọdẹ Fún Àṣeyẹ*, bí àpẹẹrẹ, a rí ìtọ́kasí èdè-àdúgbò tàbi ẹka-èdè agbègbè ibi tí wọ́n ti wá.

(i) Ní'jọ́ tí a kú, ara bàjẹ́, ara ò **ṣiàn** (o. i. 23 ìlà 184).
(ii) Máa ríbà **yèyé** (o. i. 37 ìlà 254).
(iii) Omi ọmú ò ní korò l'áiyà **iye** rẹ̀ (o. i. 57 ìlà 194)
(iv) Mo jí má jagbẹ́ ó **yúnko** (o. i. 58 ìlà 217)

Nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí, asùnjálá kejì ló ṣafọ̀ àpẹẹrẹ àkókó àti ìkejì tó jẹyọ níbi ìjálá ìsìnkú. Ọ̀kọrin kínní ló sì ṣafọ̀ àpẹẹrẹ kẹta àti ìkẹrin tó jẹyọ níbí ìjálá ikómọjáde. Èyí fún wa ní òye pé, asùnjálá àkókó ló kópa níbi ìjálá méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀; bẹ́ẹ̀ náà sì lọ́rọ́ rí fún asùnjálá kejì pẹ̀lú. Bí a kò tilẹ̀ lè tọ́ka ìlú pàtó tí àwọn asùnjálá kejì ti wá, a lè sọ pé, ó wá láti apá ìsọ̀rí tàbí ìpín ẹka-èdè apá Gúṣù-ìlà- oòrùn ilẹ̀ Yorùbá (SEY). Àwọn ìlú tó wà lábẹ́ ìsọ̀rí yìí ni: Rẹ́mọ, Òǹdó, Ọ̀wọ̀ àti Ìkàrẹ́. Àwọn ẹka-èdè yìí ló máa ń ṣàmulò 'siàn' àti 'yèyé' dípò 'ṣunwọ̀n' àti 'ìyá' tàbí 'mọ̀mọ́' tí Yorùbá àjùmọ̀lò máa ń ṣàmúlò (Adétugbọ̀ 1982, o. i. 221 àti 222). A lè sọ pé, Òǹdó ni aṣafọ̀ yìí ti wá, nítorí pé, ibẹ̀ ni àmúlò 'ṣiàn' ti wópọ̀ jùlọ bí ọ̀nà-ìṣafọ̀. Àwọn ẹka-èdè wọ́nyí ló máa ń ṣàmúlò ìró 'ɣ' dípò 'w' Yorùbá àjùmọ̀lò; bó ṣe jẹyọ láwọn àpẹẹrẹ ìṣàlẹ̀ wọ́nyí:

S/N	Yorùbá Àjùmọ̀lò	Ẹka-èdè Gúṣù-ìlà-oòrùn Yorùbá
(i)	Owó	o ɣ ó
(ii)	àwọ̀	àɣɔ̀
(iii)	Wò	ɣò
(iv)	Eéwo	oɣiɣó
(v)	sunwọ̀n	siɣàn

Lọ́nà mìíràn, ó ṣeé ṣe kó jẹ́ Òkìtìpupa ni ọ̀kọ̀rin kìnní ti wá; nítorí pé, ẹka-èdè yìí ló máa ń ṣàmúlò 'yún' dípò 'lọ' Yorùbá àjùmọ̀lò àti ìlò 'iye' dípò 'mọ́mọ́' tàbí 'ìyá' ní Yorùbá àjùmọ̀lò. A rí i dájú pé, èdè-àmúlò jẹ́ òdiwọ̀n tí a lè ṣàmúlò láti ṣe ìdámọ̀ ìṣọwọ́ akópa.

ÌKÁDÌÍ

Iṣẹ́ ìwádìí yìí ti ṣàgbéyẹ̀wò itayọ kókó-ọ̀rọ̀ àti àwòmọ́ akópa tí afọ̀ ajẹmọ́jàálá máa ń ní. Ó hàn gbangba pé, kókó-ọ̀rọ̀ ìjálá máa ń dá lé oríkì oníruurú (ohun abẹ́mí ati ohun aláìlẹ́mìín) àti orílẹ̀ bí ìsọ̀rí afọ̀ ajẹmóríkì tó máa ń gba itayọ ninú afọ̀ ajẹmọ́jàálá; nígbà tí oríkì ajẹmáyẹyẹ máa ń tayọ ṣíkejì, tí oríkì ajẹmọ́rèmọ̀jé tàbí ìṣípà-ọdẹ máa ń jẹyọ kéyìn. Èyí kò ṣàdéédé rí bẹ́ẹ̀, ewì ìjálá awo-ẹgbẹ́ ọdẹ ni ìrèmọ̀jé jẹ́. Kò sí ohun tàbí ẹni tí afọ̀ ìjálá kò le kì. Èyí ṣàfihàn àwọn asùnjálá (ọdẹ) bí àwọn tó ṣèkáwọ́ agbègbè tàbí àyíká wọn.

Síwájú sí i, a rí i pé, àwọn ọdẹ ló jẹ́ akópa ìjálá, ṣé ẹni tó bá mojúbọ Ògún, là á jẹ́ kó yanbì nírè. Àtilẹ́yìn èrò yìí ni Alan àti Fabb (1990, o. i. 196) ṣe pé, ohun tó ń ṣe atọ́nà aṣafọ̀ ni ipò tó bá ara rẹ̀ (Kí ló fi afọ̀ ṣe?) àti irú ẹni tó jẹ́ (Ta ni aṣafọ̀ í ṣe ?). Wọ́n ní: "We can distinguish two principal types of language variation: variation according to who you are and variation according to the situation you find yourself". (A le fiyàtọ̀ ìyapa èdè hàn lọ́nà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀: ìyapa nípaṣẹ̀ ẹni tí o jẹ́ àti ìyapa nípasẹ̀ ipò tí o bára rẹ̀). Èyí fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé, omi àti aró ni akópa àti èdè afọ̀. Ohun tó ṣatọ́nà

ìṣọwọ́ afọ̀ ni aṣafọ̀ àti àyè tàbí ipò tí aṣafọ̀ bá ara rẹ̀, bí a ti ṣàgbékalẹ̀ ìṣàpèjúwe àwọn asùnjálá àti ipò ìjẹyọ ẹyà afọ̀ ìjálá tí wọ́n sun. Kò sí bí a ṣe lè ṣe ebòlò, kó mọ́ rùngbẹ́. A lè fi èdè akópa ṣàpèjúwe rẹ̀ ninú afọ̀ ìjálá. Lọ́nà mìíràn, ìyẹyọ ẹka-èdè inú ìjálá fihàn pé owó tí a pe ẹyẹ àdàbà ninú àlọ́ àpamọ̀ ni ewì ìjálá jẹ́; kò sójà tí kò ná tán jákè-jádò ilẹ̀ Yorùbá.

ÀWỌN ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adétugbọ̀, A. (1982). "Towards a Yorùbá dialectology". Ninú A. Afọ́láyan (Olótùú.) *Yorùbá Language and Literature* Ìbàdàn: University Press. o . i. 207-224.

Ajíbádé, G. A. (2012). "The Yorùbá oral Artist and their use of words" (ọ̀rọ̀). Ninú A. Adéjùmọ̀ (Olótùú.) *Yorùbá: Jọ́nà ẹgbẹ́ onímọ̀ èdè Yorùbá.* Ìbàdàn: Hakolad Prints. Vol.7. No. 1., o. i. 30-62.

Alan, D&Fabb, N. (1990). *Literary studies in action.* New York: Routledge.

Ajàdí. G. (1997). Ògúndáre Fọ́yánmu's Ibà Olódùmarè: A stylo-rhetorical Analysis. Ninú L. Adébáyọ̀ (Olótùú.) *Stylistics in theory and practice*. Ìlọrin: Paragon Books, o. i. 205-208.

Àjùwọ̀n, B. (1981a). *Ìrèmọ̀jé eré Ìṣípà Ọdẹ*. Ìbàdàn: University Press.

Àjùwọ̀n, B. (1981b). "The Ìjálá (Yorùbá Poet)". Ninú U. Abalogu, G. Ashiwájú & R. Amadi-Tshiwala (Àwọn Olótùú.) *Oral Poetry in Nigeria*. Lagos: Emacon Print Limited, o. i. 196-208.

Ayọ̀dàbọ̀, J. (1997). "Pragma-Linguistic study of Abíọ́lá's historical speech of June 24, 1993". Ninú L. Adébáyọ̀ (Olótùú.) *Stylistics in theory and practice*. Ìlọrin: Paragon Books, o. i. 132-138.

Awóyalé, Y. (1991). "Ìfojú Ìmọ̀-ẹ̀dá-èdè-ajẹmáfọ̀ wo ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ lítírẹ́ṣọ̀". Ninú S. Ajéwọlé (Olótùú.) *Láderin*: Ìwé àtigbàdégbà ẹgbẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ìjìnlẹ̀ Yorùbá ti Yunifásitì Ilọrin, Ilọrin: Oyes Modern Printers, o. i. 3-5 & 32-36.

Babalọlá, A. (1966). *The content and form of Yorùbá Ìjàlá.* Oxford: Clarendon Press.

Babalọlá, A. (1973). *Orin Ọdẹ Fùn Àṣeyẹ.* Lagos: Macmillan Nigeria Publishers Limited.

Babalọlá, A. (1982). "The delights of Ìjálá". Nínú W. Abímbọ́lá (Olótùú) *Yorùbá Oral Tradition.* Ilé-Ifẹ̀: Ìfẹ̀ African Languages and Literatures Series No.1. o. i. 631-676.

Callow, C. (1974). *Literary style: A symposium.* London: Oxford University Press.

De Beangrade, R. & Dressler, W. (1981). *Introduction to text-linguistics.* London: Longman.

Finnegan, R. (1970). *Oral Literature in Africa.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

---------- (1977). Oral Literature: Its Significance and Social context. Ìbàdàn: University Press Limited.

Geoffery, N. & Short, M. (1981). *Style in fiction: A linguistic introduction to English fictional prose.* New York: Longman group Limited.

Halliday, M. A. K. (1970). *A course in spoken English intonation.* London: Oxford University Press.

Halliday, M, A. K. &Hassan, R. (1976). *Cohesion in English Language.* London and New York: Longman.

Ilésanmí, T. M. (2004). *Yorùbá orature and literature: A cultural Analysis.* Ilé-Ifẹ̀: University of Ifẹ̀ Press.

Ọlágbèmí, T. (2000). "Adébóyè Babalọlá: Ògúnlànà aṣàtúpalẹ̀ lítírẹ́ṣọ̀ alohùn Yorùbá" . Nínú A. Oyèrìndè (Olótùú) *O pegedé.* Lagos: Longman, o. i. 84-93.

Ọlájubù, O. (1981). "Yorùbá oral poetry: composition and performance". Nínú U. Abalogu, G. Ashiwájú & R. Amadi-Tshiwala (Àwọn Olótùú.) *Oral Poetry in Nigeria.* Lagos: Emacon Print Limited, o.i. 75-85.